# ẸWÙ ATI AṢỌ ÌGÚNWÀ AWỌN ALUFAA ISRAẸLI

## Ẹksodu 28:1-43; 29:29, 30; 39:1-31

### ẸKỌ 97 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Aarọni yio si ma rù idajọ awọn ọmọ Israẹli li àiya rẹ̀ nigbagbogbo niwaju OLUWA" (Ẹksodu 28:30).**

**I Ẹwu Mimọ́ fun Olori Alufaa, fun Ogo ati Ọṣọ**

1. Gbogbo ẹwu awọn alufa ni a dá nipasẹ ọrẹ atinuwa awọn eniyan, ati lati ọwọ́ awọn ẹni ti a ti yà sọtọ ti wọn si mọ iṣẹ ọna i ṣe daradara, Ẹksodu 28:1-5; 39:1; 25:2, 4, 7; Ẹsra 2:68, 69; Nehemiah 7:70-72
2. Ẹwu-ẹfodi ati Ọja-amure jẹ́ aṣọ ti o lẹwa ti a si fi ọgbọ́n ṣiṣẹ ọnà si: okuta ti a fín orukọ sí si wà ni ara rẹ̀ ni ejika, Ẹksodu 28:6-14; 39:2-7; 35:4, 5, 9
3. Igbaya Idajọ ni a fi wura, aṣọ alaro ati elese aluko ati ododó ati aṣọ ọgbọ olokun wíwẹ́ ṣe, pẹlu okuta iyebiye mejila lati duro fun ẹ̀yà Israẹli mejila; a so igbaya naa pẹlu ọ̀ṣọ́ wọnyii mọ́ ẹwu-ẹfodi, Ẹksodu 28:15-29; 39:8-14; Isaiah 49:16
4. Urimu ati Tummimu ni a fi sinu igbaya, Ẹksodu 28:30; Lefitiku 8:8; Numeri 27:21
5. Aṣọ-igunwa Ẹwu-ẹfodi jẹ aṣọ-alaro ti a ṣe lọṣọ daradara, a si n wọ̀ ọ́ tẹlẹ ẹfodi, Ẹksodu 28:31-35; 39:22-26; Lefitiku 8:7-9
6. Fila, tabi ibori ti a fi aṣọ ọgbọ didara ṣe, Ẹksodu 28:39; 39-28
7. Awo Finfin Kiki Wura ni a fi ọja alaro so mọ́ fila, Ẹksodu 28:36-38; 39:30,31
8. Ẹwu-awọtẹlẹ ati Ọja-amure ati Ṣokoto Ọgbọ daradara, ti o si ni iṣẹ-ọna abẹrẹ ni wọn n wọ̀ si abẹ́ aṣọ igunwa ẹwu ẹfodi, Ẹksodu 28:39, 42, 43; 39:27-28
9. Lẹyin ikú olori alufaa a maa n fi awọn aṣọ mimọ́ yii fun ẹnikẹni ti yoo gba ipò rẹ̀, Ẹksodu 29:29, 30; Numeri 20:24-28

**II Aṣọ Mimọ́ fun Awọn Alufaa, fun Ogo ati fun Ọṣọ**

10. **Ẹwu Ọgbọ, Ṣokoto ọgbọ, Fila ọgbọ ati Ọja-amure** ni a dá fun awọn ti yoo maa ṣe iṣẹ alufaa, Ẹksodu 28:4, 40-43; 39:27, 28; Lefitiku 8:13; Esekieli 44:17-19

## ALAYE

**Pipé Ẹwà ninu Isin Ọlọrun**

Ninu awọn ẹkọ wa atẹyinwa nipa awọn Ọmọ Israẹli, a ri wọn bi wọn ti n fi ẹsẹ̀ Oke Sinai silẹ ti wọn si n lọ si Ilẹ Ileri lẹyin ti wọn ti gba Ofin ati ilana Ọlọrun. Wọn ti kọ́ Agọ-ajọ wọn si ti gbé e kalẹ, Ọlọrun si ti fi ara Rẹ hàn lọna iyanu lori ati ninu ile ọ̀wọ yii. Nikẹyin, ọwọ̀n awọsanma ṣí kuro o si n lọ siwaju, Ọlọrun si n ṣamọna wọn lọ. Awọn ọmọ Lefi ti tẹwọ gba iṣẹ titun ti a fifun wọn, ohun gbogbo si n lọ gẹgẹ bi eto.

Lati igba iya-si-mimọ́ Agọ-ajọ titi di igba ti wọn ṣí kuro, ni aipé oṣu meji, (Fi Ẹksodu 40:2 we Numeri 10:11), Ọlọrun ti ba wọn pade nigba pupọ nigba ti wọn mu ọrẹ wá siwaju Rẹ̀. Ni akoko yii ni awọn ijoye Israẹli mu ọrẹ wọn tọ Oluwa wá (Numeri 7:1-89); wọn ṣe Ajọ Irekọja keji; a fi ororo yan olori alufaa ati awọn alufaa oluranlọwọ, a si yà wọn sọtọ fun iṣẹ isin wọn; a yan awọn ọmọ Lefi a si kọ́ wọn ni iṣẹ́ wọn fun Ọlọrun. Wọn ti rú ẹbọ owurọ ati ti aṣalẹ ojoojumọ, wọn ti mu ọrẹ Ọsẹ wá fun Oluwa ati ọrẹ ibẹrẹ oṣu titun. Bi o ti ṣe pe a ṣẹṣẹ dá isin naa silẹ, wọn ti ri apẹẹrẹ Ẹbọ Pipe naa ti n bọ wá lati Ọrun, ti a ṣe apẹẹrẹ rẹ̀ niye igba.

Dajudaju gbogbo ohun ti a lò nibi isin naa ati itumọ wọn kò yé wọn tán patapata. Wọn fi igbagbọ tẹle eto naa nitori eto Ọlọrun ni. Awa ti a wà nigba ayé Ihinrere maa n ṣe bakan naa bi a ba jẹ́ ọmọ Ọlọrun. Wọn mọ̀ pe iṣẹ wọn si Ọlọrun ni lati fi igbagbọ tọ Ọ wa pẹlu igbọran si eto Rẹ̀, bi gbogbo rẹ̀ ko tilẹ yé wọn tan. Awa naa mọ̀ pe bẹẹ ni o ri. Bẹẹ gẹgẹ, bi wọn ko tilẹ mọ ohun ti gbogbo apẹẹrẹ ati ojiji naa n tọka si, sibẹ wọn le jẹ anfaani kan naa lati inu Ẹjẹ Kalfari gẹgẹ bi awa ti o ti mọ̀ lati inu itan pe ohun ti o ṣẹlẹ ni.

Igba miiran, boya wọn a wo awọn nnkan ti a n lò nibi ijọsin pẹlu iyanu, gẹgẹ bi awa naa ti n wo nnkan wọnni ti ọjọ iwaju ti a ti sọ tẹlẹ nipa rẹ̀, pẹlu itara, ti a n fẹ mọ̀ bi awọn nnkan wọnni yoo ti ṣẹ. Dajudaju bi wọn ti n dé ẹnu ọna agbala Agọ-ajọ, ẹnu ya wọn si ẹwa ohun gbogbo ti o wà ni ile naa ati eto iṣẹ isin ibẹ. Boya wọn tun wo aṣọ alarabara ti awọn alufaa wọ̀ pẹlu iyẹsi, ati lara agbada mimọ́ ẹlẹwa yii, wọn le ri apẹẹrẹ ọpọlọpọ ninu iwa Kristi ti n bọ̀ wá. Bi awọn agbada wọnyii ba si mu wọn ronu lori ileri gbogbo ti a ṣe fun wọn nipa Alagbawi naa ti o n bọ, ki ni ero wọn yoo ti jẹ́ nigba ti wọn ba ri olori alufaa ti a wọ̀ ni aṣọ ogo ati ẹwa ti o n ṣiṣẹ isin?

**Aṣọ Oyè ti Olori Alufaa**

Olori Alufaa ni i ṣe aṣiwaju ninu ipò oyè alufaa; ati lati fi ipò ti rẹ̀ hàn, Ọlọrun paṣẹ pe ki aṣọ olori alufaa ki o lọla ju ti gbogbo awọn iyoku lọ, ṣugbọn eyi nikan kọ́ ni idi ti iyatọ fi wà laaarin aṣọ ti rẹ̀ ati ti awọn alufaa yoku. A ti sọ pe ìba ẹwà ranpẹ ti o wà lara aṣọ awọn alufaa ti n ṣiṣẹ nigbakuugba fi diẹ ninu iwa Kristi hàn. Ṣugbọn ko ṣe e ṣe fun ẹni kan ṣoṣo tabi ẹbọ kan ṣoṣo lati fi gbogbo iwa Kristi hàn tabi iṣẹ Rẹ̀ gẹgẹ bi alagbawi. Ohun ti o tobi ju lọ ti ẹni kan ṣoṣo le jẹ apẹẹrẹ rẹ̀ ni a fi hàn lara olori alufaa. Oun ninu aṣọ oyè rẹ̀ ati aṣọ iyebiye, jẹ́ apẹẹrẹ Olori Alufaa wa giga ti a ṣe lọṣọ ologo ju lọ nisisiyii, ọṣọ ododo ayeraye, -- ẹwa eyi ti ẹni kan kò le ronu rẹ̀, tabi ki a ri ẹwu ti ayé èṣẹ yii tabi okuta iyebiye ti ayé ègún yii to le fi ogo naa hàn.

Ninu Lefitiku 8:7-9 a sọ fun ni bi wọn ti ṣe n wọ aṣọ wọnyii letoleto. Leke awọtẹlẹ, Mose wọ Aarọni ni ẹwu awọtẹlẹ ọgbọ ọlọna o si fi amure ọgbọ ti aṣọ alaro, elese aluko ati ododo di i ni ẹ̀gbẹ́. Lori eyi, Mose si tun wọ̀ ọ́ ni ẹwu-efodi, aṣọ igunwa pẹlu pomegranate ti a ṣe ni awọ alaro, elese aluko ati ododo ni iṣẹti rẹ̀ ti a si so ṣaworo wura mọ. Awọn ẹlomiran gba pe ṣaworo wura mejilelaadọrin ati pomegranate ni o wà ni iṣẹti-aṣọ igunwa kan ṣoṣo.

Loke ẹwu-efodi ni efodi tikara rẹ wa. Ẹwu penpe ni ṣugbọn o jẹ́ ọ̀kan pataki ninu awọn aṣọ olori alufaa. A ṣe e lọṣọ pẹlu wura, aṣọ-elese aluko, aṣọ ododo, aṣọ alaro ati aṣọ ọgbọ wiwẹ gẹgẹ bi Ọlọrun ti paṣẹ fun Mose lori Oke Sinai. A fi okuta iyebiye meji si ejika ẹwu-efodi naa. Ni ara okuta yii ni a kọ orukọ ẹya Israẹli mejila sí. Efodi yii ni ọja ti rẹ̀ ti a fi n gba a, eyi ti a ṣe oniruuru iṣẹ ọna si lara.

Igbaya idajọ ni a fi okun ẹwọn wura ti a fi kọ oruka wura so pọ̀ mọ́ efodi. Gigun rẹ̀ jẹ iwọn inṣi mejidinlogun o si fẹ̀ ni iwọn inṣi mẹsan-an, a si ṣẹ ẹ si meji ọgbọọgba. Lori rẹ̀ ni a fi okuta mejila ti a gbẹ́ orukọ awọn ẹya Israẹli si. Nibi kan lara igbaya idajọ yii ni Mose fi Urimu ati Tummimu si, eyi ti Iwe Mimọ́ kò ṣe alaye pupọ fun ni nipa rẹ̀.

Ohun ti olori alufaa i maa fi dé ori rẹ̀ ni fila tabi ibori ti a fi aṣọ ọgbọ daradara ṣe, lara eyi ti a si fi ọja alaro so awo wura ti a kọ "MIMỌ́ SI OLUWA" si lara.

**Kristi, Olori Alufaa Wa**

A ti ṣe arosọ nipa ohun ti ẹni kọọkan ninu awọn eniyan naa yoo maa rò nigba ti wọn ba n wo ogo ti o hàn lara ẹwu ati aṣọ igunwa awọn alufaa wọnyii. Diẹ ninu awọn ohun ti wọn n tọka si ti ṣẹ ná, a si tun ni imọ kikun diẹ si i ju awọn Ọmọ Israẹli ti igba naa lọ nipa ohun ti wọn duro fun. Ṣugbọn awa ko ti i ri ogo kikun naa, eyi ni awa yoo si ri ni ẹkun rẹrẹ nigba ti a ba ri Ẹni naa ti I ṣe Olori Alufaa wa nisisiyii ni oke ọrun lọhun. Oun wa ninu aṣọ oye alufaa ti a fi fun Un nigba ti a jẹ Ẹ niya ti O si di Alagbawi wa (Ka Isaiah 63:1; Heberu 2:17; 3:1, 2; 4:14, 15; 7:24-28; 8:1, 2, 9:11-14; 10:19-21).

**Diẹ ninu Apẹẹrẹ wọnni ti a ti Muṣẹ Lapa Kan**

**Aṣọ Ọgbọ** naa ni itumọ pataki. A fi ye ni pe apẹẹrẹ rere Iyawo Kristi ni eyi duro fun (Owe 31:12). Awọn alufaa Ọlọrun ati awọn ẹni nla ti igba ni a maa n wọ aṣọ ọgbọ ninu iṣẹ ijọsin wọn (1 Samuẹli 2:18; 22:18; 2 Samuẹli 6:14; Esekiẹli 44:17, 18). On ni awọn ayanfẹ Ọlọrun i maa wọ pẹlu bi ohun ọṣọ olowo iyebiye (Esekiẹli 16:10-14; Ifihan 19:14). On ni i ṣe ododo awọn eniyan mimọ ni Ọrun (Ifihan 19:8).

**Ni ara Aṣọ Ejika** ati **Igbaya Idajọ** ni a kọ orukọ ẹya Israẹli **mejila** si. A ki i tú wọn kuro lara efodi, eyi si jẹ fun iranti ati ami lati jẹ ki awọn Ọmọ Israẹli mọ pe a n ṣe iranti wọn nigba ti olori alufaa ba tọ Ọlọrun lọ. Nipa bayii alagbawi wọn ru ẹbẹ wọn ni ejika ati ookan aya rẹ̀.

**Urimu ati Tumimu,** ti a kò mọ pupọ nipa wọn bi wọn ti ri tabi ohun ti o wà ninu wọn, jẹ iyanu pupọ. Ninu igbaya idajọ ni Mose fi wọn si, awọn si ni ohun ti olori alufaa fi i maa ba Ọlọrun sọrọ. Bi wọn si ti ṣe pataki to ko fara sin nitori wọn ja si imọ ẹmi ati itọni ti a n fi fun awọn ti agbara Ẹmi Ọlọrun n gbe inu wọn, ti wọn ni ifororo yan ti Ẹmi Mimọ́ ti wọn si n bá Ọlọrun rin timọtimọ. O rọrun lati mu iṣura iyebiye mimọ ti Ọlọrun n fi fun ni yii binu ki a sọ ọ nu – Urimu ati Tumimu wa lara nnkan marun-un ti awọn akẹkọọ Bibeli sọ fun ni pe o wa ni Tẹmpili Sọlomọni ati ninu Agọ, ṣugbọn ti kò si ninu Tẹmpili keji.

O di mimọ̀ fun ni pe ọpọlọpọ eniyan ni aye igba nì ni Ọlọrun bá sọrọ nipa Urimu ati Tumimu (Awọn Onidajọ 20:18, 28; I Samuẹli 10:22, 23; 23:9-12; 30:7, 8). Wọn jẹ iṣura nipa ti ẹmi ti o ṣọwọn fun wọn lọpọlọpọ; bakan naa ni o si ni lati jẹ fun wa (Ẹsra 2:63; Deutonomi 33:8; 1 Samuẹli 28:6). Bawo ni ọkàn wa ti gbọdọ kun fun ọpẹ to pe iṣura iyebiye yii ko ba Majẹmu Laelae kọja lọ, ṣugbọn a fi i pamọ fun awọn ti o ba le fi tọkantọkan ṣafẹri ohun ti o dara ju lọ ti Ọlọrun ti pese silẹ fun ni (1 Kọrinti 2:14; Johannu 8:12; 16:13-15; 1 Johannu 3:24; 4:1; 1 Tẹssalonika 5:21).

**Aṣọ Igunwa Ẹwu-Efodi** ni a so ṣaworo wura ati pomegranate ti a fi la ara wọn mọ iṣẹti rẹ̀. Nigba ti olori alufaa ba n ṣiṣẹ isin rẹ̀ niwaju Oluwa awọn ṣaworo yoo maa lù, awọn eniyan ti wọn wa ni agbala ode ti wọn si n gbadura yoo mọ daju pe alagbawi wọn n gba ọrọ wọn sọ lọwọlọwọ niwaju Oluwa. Iro ṣaworo pẹlu yoo jẹ ki awọn eniyan mọ

pe olori alufaa wa laaye sibẹ.  Bi iro naa ba dakẹ lojiji, eyi yoo fi han pe ó ti kú, ẹlomiran si ni lati gba ipò rẹ̀ lẹsẹ kan naa.

Nipa adura ati idapọ pẹlu Ọlọrun awa naa pẹlu le mọ pe Olori Alufaa wa giga n bẹbẹ fun wa.  Awa naa pẹlu le gbọ́ iro "aago" ti o wa ni iṣẹti aṣọ Rẹ nigba ti a ba sun mọ Ọrun.

**Fila** ti o wà lori olori alufaa jẹ ọ̀kan ninu awọn olubori aṣọ ti eniyan Ọlọrun yii n wọ̀.  A so **awo wura** kan mọ ọn a si kọ "MIMỌ́ SI OLUWA" si i lara.  Eyi jẹ iranti fun un nigba gbogbo ati fun gbogbo awọn ti o ri i pe ipò mimọ́ ati ayè giga ni ó wà.

Ninu ohun **mimọ́** ni olori alufaa n ṣe iranṣẹ.  Oun ni aṣoju Ọlọrun **mimọ́**, Oun ni o ni lati ṣe irubọ ki a ba le ṣetutu lati mu ẹ̀ṣẹ kuro, ki a ba le sọ awọn ti o mu ẹbọ wa tọkantọkan ati pẹlu igbagbọ di **mimọ́**. Oun ni o ni lati kọ awọn eniyan ni ọna ododo ati iwa **mimọ́** tootọ.  Gẹgẹ bi alagbawi, oun paapaa ni lati jẹ́ **mimọ́**, ki o le ri oju rere gba fun wọn, ki a le sọ wọn di **mimọ́** ki a si pese wọn silẹ lati ba awọn eniyan **mimọ́** gbe ninu ijọba ti o logo.  Ni akotan, oun jẹ apẹẹrẹ **Ẹni mimọ ati ododo** ni, ti yoo wá nigba ti akoko Ọlọrun ba to lati mu ẹṣẹ kuro ki O si sọ wa di **mimọ́** nipa ẹbọ ti Oun yoo fi ara Rẹ̀ ru.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni pese awọn ohun ti a fi da aṣọ awọn alufaa?
2. Darukọ awọn aṣọ ti awọn alufaa n wọ̀.
3. Darukọ awọn aṣọ ti olori alufaa n wọ̀.
4. Eredi awọn okuta ti o wà ni ejika?
5. Ki ni a fín sara ọ̀kuta ti o wà laya olori alufaa, eredi rẹ̀ ti o si fi wà nibẹ?
6. Sọ ohun ti aṣọ ọgbọ duro fún.
7. Lọna wo ni a gbà fi iwa mimọ́ Ọlọrun hàn lara aṣọ olori alufaa?
8. Ki ni ṣe ti Ọlọrun paṣẹ pe ki a ṣe awọn aṣọ wọnyii patapata bi Oun ti n fẹ́ gan an?
9. Eredi ṣaworo ti o wa ni iṣẹti aṣọ alaro ti olori alufaa maa wọ̀?
10. Sọ awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti o fi hàn wa ẹni ti Olori Alufaa wa i ṣe.